# Ipa Tí Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀-Tọ́rọ́-fọ́nkálé Ń Kó Lórí Níní Ìmọ̀ Tó Jinlẹ̀ Nípa Àwọn Ẹranko

**Àjàyí, F.T. *Ph.D.***
*funmifayomiajayi@gmail.com*
àti
**Fasehun, Mercy Ayọ̀, *Ph.D.***
*fasehunmercy@yahoo.com*
*Department of Yorùbá*
*Adéyẹmí College of Education*
*Ondo, Ondo State*

## Àṣamọ̀

*Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn ọmọ ènìyàn ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀. Ọ̀rọ̀ sísọ láàrin àwọn ẹ̀dá jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì nínú ìgbòkègbodò wọn. Lótìítọ́ ni pé kí àwọn òyìnbó tó gòkè wá ni ìran Yorùbá ti ní ọ̀nà lóríṣiríṣi tí wọ́n ń lò láti máa fi bá ara wọn sọ̀rọ̀. Yorùbá ń fi ẹnu, ojú, ara, ẹsẹ̀, orí, ọwọ́, àti ohùn bá ara wọn sọ̀rọ̀ láti fi ìmọ̀lára, ẹ̀kọ́, ìtàn, ìwà ọmọlúàbí, àti ẹ̀dùn ọkàn wọn hàn. Ṣùgbọ́n ayé ti kúrò níbi tí àwọn àgbà ọjọ́un fi sí, ọpọ́n ìmọ̀ ti sún nítorí pé ìmọ̀ ẹ̀rọ ti jẹ́ kí àwọn ènìyàn àwùjọ ní ìmọ̀ nípa ayé, ẹ̀dá ènìyàn, ẹranko, ewé, omi, igi, àpáta àti ohun gbogbo tí ó ń lọ ní àyíká wọn. Lára àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ayé òde òní ni a ti rí ìtàkùn àgbáyé lábẹ́ èyí tí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́fọ́nkálé ti jáde, àwọn bíi Facebook (ẹ̀rọ ìbánidọ́rẹ̀ẹ́), whatsapp, twitter, blackberry messenger, yahoo, instagram, 2go, snap chat àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú iṣẹ́ yìí ni a ti wo bí a ṣe lè ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ẹranko láti ipasẹ̀ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀*

*tọrọ́-fọn-kálé. Bákan náà ni a wo orísirísi àwọn ẹranko èyí tí a kò lè rí lójúkorojú ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé nípa ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé ní a ti lè rí àwòrán wọn dáradára àti irú ẹranko tí wọ́n jẹ́. Iṣẹ́ yìí wá fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé àǹfààní ńlá-ǹlà ni ìmọ̀ ẹ̀rọ jẹ́ fún ayé tí a wà nínú rẹ̀ yìí.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé, Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀, Ẹranko.

## Ìfáárà

Ayé kò dúró sójú kan nítorí pé ojú ń là si ni lójoojúmọ́. Ìmọ̀ ẹ̀rọ ti sọ ohun gbogbo dẹ̀rọ̀, ọgbọ́n sì ti di ohun tí à ń fi ojoojúmọ́ mu bí omi, nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ tí àwọn Òyìnbó ṣètò rẹ̀ fún gbogbo àgbáyé láti máa fi bá ara wọn sọ̀rọ̀ láwùjọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbọ́n àti ìmọ̀ ni a lè rí nínú àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé. Lára àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ayé òde-òní ni a ti rí ẹ̀rọ ìléwọ́, ojú ìwé, ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá, ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì, ẹ̀rọ amóhùn-máwòrán, *whatsapp*, *2go*, *instagram*; ìtàkùn àgbáyé èyí tí ó jẹ́ olórí wọn ni ó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n nínú iṣẹ́ yìí. Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé ni a lè pè ní ọ̀nà àgbàṣafọ̀ nípa ìṣàmúlò ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà àti ẹ̀rọ ìléwọ́ láti ṣe àjọpín ẹ̀kọ́, èrò, ìmọ̀ ọgbọ́n òye àti àwọn ọ̀nà ìgbọ́rọ̀kalẹ̀ nípasẹ̀ tàbí nílànà àwòrán pẹ̀lú onírúurú iṣẹ́ àmúṣe lórí ìtàkùn àgbáyé.

Ìtàkùn àgbáyé ni igi ràbàtà tí ó ní ẹ̀ka tí ó pọ̀, èyí tí àwọn ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé so sí lórí jìngbìnnì. Ìtàkùn àgbáyé yìí ni ìmọ̀ ẹ̀rọ tí ó gbajúgbajà nínú gbogbo ìmọ̀ ẹ̀rọ tí ó wà káàkiri àgbáyé lónìí. Agba (2002:253) fi ìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí ó ṣàlàyé pé:

> Internet is the most technologically advanced medium of communication. It is multimedia information superbly way that facilitates business, sports, politics, entertainment and other endeavours across international boundaries. In fact, it is the information revolution that has turned the world into a "global village".
>
> Ìtàkùn àgbáyé ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó ga jù. Ó jẹ́ onírúurú ọ̀nà tí ó ń okùnfà okòwò, eré-ìdárayá, ìṣèlú, ìpanílẹ̀rín àti àwọn nǹkan àdáwọ́lé mìíràn, jákèjádò gbogbo àgbáyé. Kódà àyípadà nínú ọ̀nà ìlanilọ́yẹ̀ ló ti sọ ayé di "abúlé àgbáyé".

Ohun tí Agba (2002) ń sọ náà ni pé ìmọ̀ ẹ̀rọ ìtàkùn-àgbáyé ti mú kí ayélujára bí ajere, kò sí ibi tí a kò lè darí rẹ̀ sí ní gbogbo àgbáyé, èyí ni ó sì mú kí ayé wá dàbí ẹni pé ojú kan ni gbogbo ẹ̀dá ènìyàn ń gbé. A ríran rílé, a tún ríran rí oko, à ń ní ìmọ̀ nípa ara wa, bákan náà ni a tún ní ìmọ̀ nípa àwọn ẹranko. Ohun tí ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí ni wíwo bí a ṣe lè ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ẹranko lórí ẹ̀rọ ayélujára pàápàá jùlọ lórí ìtàkùn àgbáyé. Àkíyèsí ni pé kì í ṣe gbogbo àwọn ẹranko wọ̀nyí ni a lè rí ní ilé ìkẹ́rankosí, nítorí náà àǹfààní gidi ni ìtàkùn àgbáyé jẹ́. Yàtọ̀ sí wí pé kí á lọ sí ọgbà ìkó-ẹranko-sí, àǹfààní ńlá-ǹlà ni ìtàkùn àgbáyé àti àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́nkálé mìíràn ń ṣe fún àwùjọ nípa níní ìmọ̀ kún ìmọ̀ nípa ẹranko. Bákan náà ni a ó gbìyànjú láti wo ìpínsísọ̀rí àwọn ẹranko, ìhùwàsí tàbí ìṣesí àti ìrísí wọn.

## Ìpínsísọ̀rí Àwọn Ẹranko

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan, tí wọ́n sì ti sọ oríṣiríṣi nǹkan nípa ìpínsísọ̀rí àwọn ẹranko. Oríṣiríṣi àwọn ẹranko ni ó wà nílé ayé gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà láti ìgbà ìwáṣẹ̀ tí Olódùmarè ti ṣẹ̀dá ayé. Gbogbo àwọn ẹranko wọ̀nyí ni wọ́n yàtọ̀ síra wọn nípa ìrísí, ìṣesí àti nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun àmúṣagbára tí Elédùwà fi jínǹkí wọn. Ọláfimíhàn (1953:5) pín àwọn ẹranko sí ọ̀nà márùn-ún pàtàkì. Ìkíní, àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú omi, èkejì àwọn tí ó ń gbé inú ilé, ẹ̀kẹta àwọn tí ó ń gbé orí ilẹ̀, ẹ̀kẹrin àwọn tí ó ń gbé inú òfúrufú, ẹ̀kárùn-ún àwọn ẹranko tí a lè pè ní jomi-jòkè, èyí ni àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú omi tí wọ́n sì tún ń gbé orí ilẹ̀.

Ajíbádé (2005:156) sọ pé a lè pín àwọn ẹranko yìí sí ọ̀wọ́ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, àti pé a lè fi ìrísí àti ibùgbé wọn pín wọn. Ọ̀wọ́ àkọ́kọ́ ni àwọn ẹranko búburú, èyí tí kìnnìún ń ṣe ọba wọn. Ọ̀wọ́ kejì ni àwọn ẹranko ilé, èyí tí à ń sìn nínú ilé. Ọ̀wọ́ kẹta ni àwọn ẹranko afàyàfà. Ajíbádé tẹ̀ síwájú láti sọ pé ọ̀nà mìíràn tí a tún lè lò láti fi pín àwọn ẹranko ni nípa ibùgbé wọn. Ó ní èyí ni ó jẹ́ kí ó rọrùn fún wa láti lè máa sọ̀rọ̀ nípa ẹran omi (water animals), ẹran ilẹ̀ (land animals), ẹran ilé (domestic animals) àti ẹran ìgbẹ́ (wild animals). O ṣàlàyé pé a tún lè fi ìṣesí tàbí ìrísí wọn pín wọn. Bí àpẹẹrẹ, ẹran abìwo, ẹran afàyàfà, ẹran ẹlẹ́sẹ̀ méjì, ẹran ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin, ẹyẹ, eku àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìṣẹ̀dá àwọn ẹranko yàtọ̀ sí ti ènìyàn ṣùgbọ́n ẹ̀dá ọwọ́ Olódùmarè ni àwọn méjèèjì jẹ́. Ìsọ̀rí ìsọ̀rí ni a lè pín àwọn

ẹranko sí. Àjàyí (2011:43) sọ pé orísìrísì òté ni a lè lò láti fi pín àwọn ẹranko sí ìsọ̀rí pàápàá làwùjọ àwọn Yorùbá. Ó ní lára àwọn òté tí a lè lò ni ọ̀wọ́, ibùgbé àti àwòmọ́ tàbí ìrísí, bí àpẹẹrẹ àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú omi ni à ń pè ní ẹran omi, àwọn ẹranko tí ó ń gbé ní orí ilẹ̀ ni à ń pè ní ẹran ilẹ̀. Ìgbà mìíràn a lè fi ìrísí wọn pín wọn, bí àpẹẹrẹ, ẹran abìwo, ẹran afàyàfà, ẹran ẹlẹ́sẹ̀ méjì, ẹran ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ibùgbé Àwọn Ẹranko

Gbogbo ẹ̀dá alààyè tí a dá sínú ayé ni wọ́n ní ibùgbé. Inú igbó ni ibùgbé ọ̀pọ̀ àwọn ẹranko, èyí ni ó mú wọn máa jẹ ewéko, èso, irè oko bíi obì, ọsàn, ẹyìn ọ̀pẹ abbl. Ní kúkúrú, ohun tí ó wà ní agbègbè wọn ni Ẹlẹ́dàá fi àṣẹ sí pé kí wọ́n máa jẹ. Àwọn ẹranko mìíràn tí ó tóbi á tilẹ̀ máa pa àwọn kékeré jẹ. Ìgbà tí ayé di ayé òyìnbó, tí ọ̀làjú dé, ni à ń rí ọgbà ẹranko nínú èyí tí a kó orísìrísì ẹranko tí a mú láàyè sí ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga gbogbo fún ìwúlò àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn ènìyàn àwùjọ, kí wọ́n lè ní ìmọ̀ kíkún lórí ẹranko. Bí a ṣe rí àwọn ẹranko ńlá ńlá ní ibùgbé wọn náà ni a rí àwọn ẹranko kékeré bí eku tí wọ́n máa ń gbé abẹ́ igọ̀ igi, abẹ́ ìtàkùn, pàlàpálá òkúta, orí igi, inú isà, abẹ́ ìtí, abẹ́ pòpópò, inú ìtẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Orísì ọ̀nà mẹ́ta pàtàkì ni a lè pín ibùgbé àwọn ẹranko sí, àwọn ọ̀nà mẹ́ta náà ni: Aginjù, ọ̀dàn, igbó. Aginjù jẹ́ igbó kìjikìji, àwọn igi ńlá ńlá bí ìrókò, oṣè àti ìtàkùn tí ó lọ́ mọ́ ara wọn ni ó pọ̀jù ní aginjù. Ìwádìí fi hàn pé kò sí ẹ̀dá tí ó lè

dáko sí aginjù ìdí ni pé ibẹ̀ ni gbogbo àwọn ẹranko búburú pọ̀ sí jù. Àwọn ọdẹ tí ó máa ń sáábà ṣọdẹ lọ sí aginjù máa ń lọ bí ìgbà tí ènìyàn ń lọ sí ojú ogun ni. Ó máa ń gba ẹlòmíràn tó odidi ọ̀sẹ̀ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ kí ó tó padà dé. Díẹ̀ lára àwọn ẹranko aginjù ni túùkú, erin, kìnnìún, àmọ̀tẹ́kùn, ẹkùn, ìkookò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ibùgbé kejì ni ọ̀dàn, àti ilẹ̀ pápá, tí igi ńlá-ńlá kò wọ́pọ̀ sí. Àwọn igi tí ó máa ń wà ní ibẹ̀ máa ń takété sí ara wọn, èyí máa ń fún àwọn ẹranko inú ọ̀dàn láàyè láti lè sáré láti ibìkan sí èkejì. Àwọn ẹranko kéékèèké kò wọ́pọ̀ nínú ọ̀dàn, àwọn ẹranko ńlá ni ó máa ń wọ́pọ̀ bíi, ẹkùn, egbin, ìgalà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ibùgbé kẹ́ta ni igbó, èyí ni ibi tí ìgbẹ́ kò ti pọ̀ púpọ̀, tí wọn kò sì tóbi tó ti aginjù. Àwọn ẹranko kéékèèké ni ó wọ́pọ̀ jù ní igbó, àwọn ẹranko abìjà kò fi bẹ́ẹ̀ pọ̀, irú àwọn ẹranko tí a lè ṣe alábàápàdé ni ọ̀yà, ọ̀fàfà, òkété, ikún, ẹtu, ìgalà, èsùró àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Tí a bá wo gbogbo ìpínsísọ̀rí àwọn ẹranko tí a ṣe, a ó rí i pé ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin àwọn àti ènìyàn ni ó mú kí àwọn ẹ̀yà ẹranko kan ó máa gbé inú ilé pẹ̀lú àwọn ènìyàn. Gbogbo ìbáṣepọ̀ wọ̀nyí náà ni ó sì farahàn nínú àwọn lítíréṣọ̀ alohùn wa tí a sì máa ń fi kọ́ àwùjọ ní ẹ̀kọ́ pàtàkì.

## Ẹranko Afàyàfà

Ejò jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko afàyàfà, àwọn wọ̀nyí pọ̀ lọ jańtirẹrẹ, lára wọn ni a ti rí olúfà, òjòlá/erè, ọká, paramọ́lẹ̀,

sèbé, ọsan, mọ̀nàmọ́ná àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ejò yìí ni ó ní oró púpọ̀. Àwọn ejò ní eyín lẹ́nu, méjì nínú àwọn eyín ejò ni à ń pè ní ọgàn. Eyín ọgàn méjì yìí gùn wọ́n sì ní ihò nínú, inú ihò sì ni oró máa ń gbà jáde. Nígbà tí ejò kò bá le ọgàn rẹ̀, yóò ká wọn kò, a sì sún wọn sí abẹ́ èrìgì rẹ̀, nítorí ààyè tí ó wà ni wọ́n ṣe ní àǹfààní láti lè ká ọgàn yìí sínú. Ọká gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ejò kan jẹ́ ẹranko tí ó máa ń ṣe eyín rẹ̀ báyìí, tí àwọn ènìyàn kò bá sì rí ọgàn ní ẹnu rẹ̀ mọ́, wọ́n á máa sọ wí pé ọká náà wọ́n eyín rẹ̀ mì. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé iye eyín tí ọká bá ti wọ́mi ń sọ iye ọdún tí ọká náà ti lò láyé. Àyà ni ejò fi máa ń wọ́ ní orí ilẹ̀, bí ejò bá ń sáré lọ, a ó máa gbọ́ ariwo tí yóò dàbí ẹni pé ejò náà ń kùn ṣùgbọ́n ìpẹ́ rẹ̀ tí ó ń wọlẹ̀ ni ó ń pa ariwo.

Ọ̀nì náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko afàyàfà, ó fara jọ agílíntí, ṣùgbọ́n ó tóbi ju agílíntí lọ. Inú odò tàbí ẹ̀bá odò ni ọ̀nì ń gbé. Ẹran ni oúnjẹ ọ̀nì. Ọ̀nì ní eyín tí ó mú, ìrù rẹ̀ sì ní agbára púpọ̀, ìrù yìí ni wọ́n fi máa ń jà. Ní ẹ̀bá odò ní orí iyanrìn ni ọ̀nì ń yé ẹyin rẹ̀ sí, nígbà tí ó bá sì di alẹ́, á bò ó kí àwọn ẹranko búburú tàbí ènìyàn má ba à rí i. Bákan náà ni Agílíntí jẹ́ ẹranko afàyàfà, ó tóbi, inú igbó sì ni agílíntí máa ń gbé, àwọn ènìyàn ní ayé àtijọ́ á máa sin agílíntí ní ilé nígbà tí wọ́n bá ti mú un láti kékeré títí yóò fi dàgbà tó láti pajẹ. Ara agílíntí kì í dán. Agílíntí fẹ́ràn omi púpọ̀, fún ìdí èyí àwọn tí ó ń sin agílíntí máa ń pọn omi fún wọn nígbà gbogbo.

**Ẹranko Ilé**

Ẹranko ilé jẹ́ ẹranko tí àwọn ènìyàn máa ń sìn nínú ilé. Ó lè jẹ́ èyí tí wọ́n ń sìn láti pa jẹ nígbà tí ó bá dàgbà, ó sì tún lè jẹ́ èyí tí wọ́n fi ń dáàbòbò ilé lọ́wọ́ àwọn ọ̀tá. Lára wọn ni Ẹlẹ́dẹ̀. Ẹlẹ́dẹ̀ jẹ́ ọ̀bùn ẹranko, ó fẹ́ràn láti máa yí nínú ẹrọ̀fọ̀. Imú ẹlẹ́dẹ̀ tóbi, imú yìí ni ó sì fi máa ń tu ilẹ̀ nígbà tí ó bá ń wá oúnjẹ. Ajá ni ẹranko ilé mìíràn, ó máa ń tẹ̀lé àwọn ọdẹ lọ sí oko ìgbẹ́. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pe ajá ní ọdẹ. Ajá jẹ́ ẹranko tí ó gbọ́ òórùn púpọ̀, ibikíbi tí ẹran bá wà, ajá yóò gbóòórùn rẹ̀ yóò sì dé ibẹ̀. Ajá mọ òórùn olówó rẹ̀ yàtọ̀ sí ti ẹlòmíràn. Ajá ní òye púpọ̀, ó sì fẹ́ràn ènìyàn. Ajá wúlò púpọ̀ fún àwọn ọmo ènìyàn, ó wà fún jíjẹ, bákan náà ni àwọn ọdẹ, àwọn alágbẹ̀dẹ àti awakọ̀ máa ń lo ajá láti fi bọ Ògún.

Ajá tún wúlò láti fi ṣọ́ ilé nítorí wí pé ajá jẹ́ òkúrorò ẹranko. Wọ́n máa ń bá a sọ̀rọ̀ bí ènìyàn, ohun tí wọ́n bá fẹ́ kó ṣe ni yóò ṣe. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń fún àwọn ẹran ọ̀sìn wọn ní orúkọ, pàápàá jù lọ Ajá. Àwọn orúkọ wọ̀nyí kì í ṣe orúkọ lásán ṣùgbọ́n wọ́n dúró fún ojú àmúwayé àwọn Yorùbá. Àwọn orúkọ tí à ń fún Ajá máa ń fi ìbáṣepọ̀ wa hàn pẹ̀lú wọn. Bí àpẹẹrẹ, Ẹ̀yìnlàárò: Èyí túmọ̀ sí pé nínú gbogbo ohun tí a bá ń ṣe láyé kí á máa ro ẹ̀yìn ọ̀la. Tańtọ́lọ́un: Orúkọ yìí ń fi hàn bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Ọlọ́run ṣe tóbi tó àti bí agbára rẹ̀ ṣe pọ̀ tó. Èyí máa ń jẹ́ kí àjọṣepọ̀ wọn jinlẹ̀ sí i kí wọ́n sì máa rí àwọn ẹranko wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ẹnìkejì wọn tàbí alájọgbélé.

## Ẹranko Abìjà

Erin jẹ́ ọ̀kan lára ẹranko abìjà, ó tóbi jù nínú gbogbo ẹranko tí ó ń gbé orí ilẹ̀, inú igbó ńlá ni erin ń gbé. Awọ erin nípọn púpọ̀, erin ní eyín méjì tí ó tóbi, eyín erin ní owó lórí púpọ̀ láyé àtijọ́ nítorí òun ni àwọn ọba àti àwọn ọlọ́lá ìlú máa ń lò láti fi ṣe ọ̀ṣọ́ sí ilé wọn. Èso igi àti ewé igi ni oúnjẹ erin. Ẹranko mìíràn ni Kìnnìún. Kìnnìún jẹ́ ẹranko tí ó ní agbára púpọ̀. Ìgbàgbọ́ Yorùbá sì ni pé kìnnìún ni ọba gbogbo ẹranko nítorí pé kì í bẹ̀rù ẹranko-kẹ́ranko. Akọ kìnnìún wà, abo kìnnìún sì wà pẹ̀lú. Akọ kìnnìún tóbi ju abo kìnnìún lọ, rọ̀rọ̀ sì wà ní ọrùn rẹ̀. Kìnnìún kì í dá rìn, ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ ni wọ́n máa ń ṣe ọdẹ. Bí kìnnìún bá ṣe ọdẹ tí wọ́n pa ẹran, gbogbo wọn ni wọn yóò jọ jẹ é. Kìnnìún kì í jẹ ẹran ọjọ́ kejì, èyí tí àwọn Yorùbá ń pè ní ẹran ìkàsì.

Bákan náà ni Ẹkùn tí Yorùbá ń pè ní ògìdán. Ẹkùn fara jọ ológbò púpọ̀, ṣùgbọ́n ó tóbi ju ológbò lọ, ó sì ní agbára jù ú lọ pẹ̀lú. Kò sí ohun tí ẹkùn kò le è fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ nítorí èékánná rẹ̀ tí ó mú àti eyín ọgàn rẹ̀. Ahọ́n ẹkùn dàbí abẹfẹ́lẹ́, èyí ni ó fi máa ń ya igbá orí ènìyàn tàbí ẹranko kẹ́ranko tó bá gbá mú nínú igbó. Òmíràn ni Ìkookò tí ó jẹ́ ẹranko abìjà. Ìkookò jọ ajá púpọ̀, ìyàtọ̀ wọn ni pé ẹsẹ̀ èyìn ìkookò kúrú ju ti iwájú lọ, òru ni ìkookò ń ṣe ọdẹ. Ìkookò á máa pa ewúrẹ́, àgùntàn àti ọmọ kéékèèkéé pẹ̀lú. Ìkookò fẹ́ràn àti máa wú òkú tí wọ́n bá ti sin, á sì jẹ é. Ìkookò jẹ́ ẹranko tí ó tutù lójú ṣùgbọ́n ìṣọ̀wọ́ ẹranko abìjà ni.

Àwọn ọ̀wọ́ ẹranko mìíràn ni ọ̀bọ, ìnàkí, ìjímèrè, ọ̀ṣá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn wọ̀nyí fẹ́ fara pẹ́ ènìyàn nítorí wí pé wọ́n ní ọwọ́ àti ẹsẹ̀, ìka ọwọ́ àti ìka ẹsẹ̀. Ojú wọn wà ní agbárí wọn, èyí jẹ́ kí wọ́n lè rí ọ̀ọ́kán dáradára. Ọpọlọ wọn jí pépé, èyí jẹ́ kí wọ́n lè darí tàbí ṣe àkóso agbègbè tí wọ́n bá wà. Wọ́n mọ àwọ̀ kan yàtọ̀ sí èkejì, wọ́n lè bá ara wọn sọ̀rọ̀ nípa àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ kan bíi lílo ọwọ́, ohùn wọn, ojú àti nípa ọ̀nà mìíràn. Ọ̀bọ àti ẹdun máa ń lo ẹsẹ̀ wọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin láti fi rìn. Ṣùgbọ́n tí wọ́n bá fẹ́ sáré wọ́n le è lo ti ẹ̀yìn nìkan. Irú ọ̀wọ́ ẹranko yìí máa ń tọ́jú àwọn ọmọ wọn, wọ́n sì tún máa ń kọ́ wọn láti kékeré. Wọn kò yàtọ̀ sí ènìyàn ní ìṣesí àti ìhùwàsí wọn.

## Ìrísí àti Ìṣesí Àwọn Àṣàyàn Ẹranko Nínú Oríkì Wọn

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú pé ìmọ̀ kò dúró sójú kan, ìmọ̀ nípa àwọn ẹranko lórí ìtàkùn àgbáyé jẹ́ àfikún ìmọ̀ ni. Ìdí ni pé àwọn Yorùbá ti ní ìmọ̀ tẹ́lẹ̀ nípa àwọn ẹranko wọ̀nyí láti ipasẹ̀ àwọn ọdẹ, àgbẹ̀ àti àwọn àgbààgbà kọ̀ọ̀kan nílẹ̀ Yorùbá. Ní abala yìí ni a ó ti sọ̀rọ̀ nípa ìrísí àti ìṣesí àwọn ẹranko díẹ̀ tí a fẹ́ mẹ́nu bà. Lára àwọn ẹranko ni a ti rí ẹranko afàyàfà, bí àpẹẹrẹ òjòlá. Òjòlá jẹ́ ọ̀kan lára mọ̀lẹ́bí ejò, ó tóbi ní ìwọ̀n bàtà mẹ́tàlélọ́gbọ̀n. Òjòlá máa ń jẹun lẹ́ẹ̀mẹ́rin sí ẹ̀ẹ̀màárùn lọ́dún. Ohun tí ẹranko yìí máa ń jẹ ni àwọn ẹranko tí ó bá tóbi, eléyìí kò yọ ọmọ ènìyàn sílẹ̀. Òjòlá máa ń ṣẹ́ eegun àwọn ẹranko tí ọwọ́ rẹ̀ bá tẹ̀ nípa lílọ́ mọ́ irú ẹranko bẹ́ẹ̀. Lẹ́yìn ìgbà tí ó bá ti ri pé ẹranko yìí kò mí mọ́,

òjòlá yóò bẹ̀rẹ̀ sí í rọ́ ọ mì. Àwòrán kan nìyí lórí ìtàkùn àgbáyé, èyí tí ó ń fi ibi tí òjòlá ti gbé odidi ènìyàn mì.



**Àwòrán 1:** Òjòlá níbi tí ó ti gbé ènìyàn mì

Ìwádìí fi hàn lórí ìtàkùn àgbáyé pé ibi tí ó bá tutù ni òjòlá máa ń gbé, bóyá nínú omi ni, orí igi tàbí inú ihò nínú apata.

**Ọká:** Lára àwọn ẹranko afàyàfà ni ọká náà jẹ́. Yorùbá sáábà máa ń fi ìrísí ọká hàn nínú oríkì rẹ̀, wọ́n sì máa ń lo ìrísí ọká nígbà mìíràn láti fi bú ènìyàn. Ọká jẹ́ ọ̀kan lára ejò afàyàfà tí ó ní oró. Yorùbá máa ń ṣe àfiwé ènìyàn tí ó bá burú pẹ̀lú ọká, wọ́n á ní: “oró inú rẹ̀ ju ti ọká lọ” nígbà tí wọ́n bá fẹ́ fi ènìyàn náà hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó lè ṣe ènìyàn ní ìjàǹbá. Oríkì ọká ìsàlẹ̀ yìí fi ọká hàn gẹ́gẹ́ bí oníwà líle.

Ọká ń bẹ nígbó
Olóògùn ò gbọdọ̀ gbé e
Ọmọ ọká dára láàfin
Nìnì sunwọ̀n léjò

Ara ń ta ọká sàsà
Ikú oró, ọká lóró, ọká dára láàfin (Àjàyí, 2015)

Yàtọ̀ sí wí pé oríkì ọká fi í hàn gẹ́gẹ́ bí ejò tó lóró, ìtàkùn àgbáyé jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn nǹkan abẹ̀mí kéékèèké bí eku àgó, eku àfè, ẹmọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni oúnjẹ ọká nínú igbó. Odù Ifá Ògúndá méjì náà tún sọ̀rọ̀ nípa ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ bí ó ṣe jẹ́ èèwọ̀ fún ejò ọká láti jẹ òkété. Ẹsẹ Ifá yìí sọ pé:

...A díá fókèété
Tí ń lọ tẹ ọká nífá
Ọká bó o bá gbáwo mì
Ibi lo ṣe
Èrìgì àlọ̀
Ọká bó o bá pewúsà wa á kú
Ọká bó o gbáwo mì
Ibi lo ṣe. (Adéríbigbé, 2008)

Ìtàn inú odù yìí ń ṣàlàyé fún wa pé nígbà kan ọká kò ní agbára kankan láti fi ṣe aápọn bí àwọn ìyókù rẹ̀. Ọká lọ dífá lọ́dọ̀ Ẹlẹ́rìí-ìpín pé kí ni kí òun ṣe kí ire lè tẹ òun lọ́wọ́, kí ohun tí òun yóò jẹ lè máa wá bá òun, kí ebi má lu òun pa. Òkété ni ó dífá fún ọká, ó ṣe ètùtù fún ọká, ó sì sọ fún un pé bíre bá wà lápá òkun yóò máa wá bá a. Ó wá sọ fún un pé ṣùgbọ́n kan tí ó wà níbẹ̀ ni pé kò gbọdọ̀ na àṣẹ ìdí rẹ̀ (ìrù) yìí sí babaláwo tàbí ẹni tí ó bá ń tẹfá pàápàá sí òun òkété. Ọká dalẹ̀ awo, ó gbé òkété mì ṣùgbọ́n kí òkété tó kú ni ó ti fi ọká ré pé nígbàkúgbà tí ó bá ti pa òkété kò ní rá mọ́ ọn nínú tí wọn yóò fi pa òun náà. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé tí ọká bá pa òkété kò lè tó ọjọ́ kejì tàbí ó pẹ́ jù ọjọ́ kẹta kí wọ́n tó pa òun náà.

Ìgbàgbọ́ Yorùbá tún hàn nínú ẹsẹ-Ifá yìí pé babaláwo ni òkété nígbà kan rí.

**Agílíntí:** Agílíntí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko afàyàfà, ó sì jẹ́ ẹranko líle. Oríṣiríṣi nǹkan ni àwọn Yorùbá máa ń ṣe àkíyèsí lára àwọn ènìyàn àti ẹranko kí ó tó di pé wọ́n gbé e jáde gẹ́gẹ́ bí oríkì tàbí orúkọ fún ènìyàn tàbí fún ẹranko. Agílíntí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko tí ìrísí rẹ̀ hànde dáradára nínú oríkì rẹ̀:

Agílíntí a bara yíyi
Ẹlẹ́gùgù a beyín hàhàhínhín
Ọmọ ìyá lòun ọ̀nì
Rogbo nírù bí abẹ (Àjàyí, 2015)

Bí ara ẹranko yìí ṣe rí bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni oríkì rẹ̀ ṣe fi hàn, eyín ẹlẹ́gùgù tòkè àti tìsàlẹ̀ sì wọnú ara wọn èyí ni ó mú kí wọ́n fi sọ pé ó rí hàhàhínhín. Bákan náà ni ìrù rẹ̀ dàbí abẹ lójú èyí tí ó lè fi gé ohunkóhun nígbà tí ó bá ń jà tàbí tí ó bá ń bínú lọ́wọ́. Àwọn Yorùbá tilẹ̀ máa ń kọrin kan ní ìbámu pẹ̀lú oríkì agílíntí, orin yìí máa ń wáyé nígbà tí asọ̀ tàbí ìjà bá wà láàrin ènìyàn méjì. Wọn á ní:

Agílíntí a-bara-yíyi
Èjìrẹ́-a-dódo-má-wẹ̀
Irú èyí kọ lẹ́tà símì

Ìrísí ẹranko yìí ni wọ́n fi máa ń bú ènìyàn tí ó bá dọ̀tí tàbí tí ó yọ̀bùn, wọ́n gbàgbọ́ pé pẹ̀lú bí agílíntí ṣe ń gbé ibi tí omi wà, síbẹ̀ ó jẹ́ ẹranko tí ó dọ̀tí. Agílíntí jẹ́ ẹranko tí ó lágbára, ṣùgbọ́n tí ènìyàn bá kọ́kọ́ rí i níbi tí ó wà, ó dàbí

ẹranko tí kò lè ṣeni ní ìjàm̀bá. Eyín àti ìrù ni agílíntí fi ń ṣagbára.

Ju gbogbo rẹ̀ lọ, a ó ri pé ohun ìjà tí àwọn ẹranko ní wọ̀nyí ni wọ́n fi ń dáàbò bò ara wọn lọ́wọ́ ewukéwu tí ó lè dojú kọ wọ́n. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní àìdẹ̀gbẹ́ jìnnà làìrábuké ọ̀kẹ́rẹ́, tí a bá dẹdò jìnnà à á rí ẹja tó yarọ. Oríṣiríṣi ni àwọn ẹranko tí à ń sọ yìí, wọ́n sì pọ̀ jantirẹrẹ nínú igbó. Bí wọ́n ṣe yàtọ̀ síra nípa ìrísí, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n yàtọ̀ síra nípa ìhùwàsí àti nípa agbára tí Olódùmarè fi fún wọn.

**Ẹtu:** Ẹtu jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko tí ìrísí rẹ̀ jẹ yọ nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá pàápàá jù lọ nínú oríkì àwọn ẹranko.

> Ẹtu láarún
> Ẹtu Òbèjé nìyéké anídẹlẹ́sẹ̀-ní-ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn
> Ẹtu Òbèjé ẹlẹ́sẹ̀ osùn
> Ò-sùn-lábẹ́-ìbà-farajòpa-ǹ-kòkó (Àjàyí, 2015)

Oríkì ẹtu tí ó wà lókè yìí sọ bí ẹsẹ̀ ẹtu ṣe máa ń rí, ẹsẹ̀ ẹtu dàbí ọ̀pá tín-ín-rín, ó gùn, ó sì máa ń mọ́ tónítóní nígbà gbogbo. Oríkì ẹtu mìíràn tún sọ pé:

> Oféfé-n-fe, arírù-tún-rase-níwájú-ọkọ
> Ẹtu òbèjé ẹlẹ́sẹ̀ ọwọ̀
> Ò gbé sẹ́ gbé ọlà, alárìnye ibi
> Pélé ojú, wọnran bí ẹni dà idẹ
> A bi àbàjà wu ọmọ ìyá rẹ̀
> Bààmú wúrà…

Ẹtu jẹ́ ẹranko tí ó sáábà máa ń gbọn ara nù nígbà gbogbo, pàápàá ìrù rẹ̀, ìdí ni pé ó jẹ́ onímọ̀ọ́tótó àti ẹranko tí

ó máa ń ṣe fáàrí. Ẹtu tún jẹ́ ẹranko tí kò fẹ́ràn kí enini máa ṣe sí i lára, ìdí nìyí tí ó fi máa ń gbọnra ní gbogbo ìgbà. Nínú ìwádìí wa, a ri pé àwọn ọdẹ ni wọ́n súnmọ́ àwọn ẹranko wọ̀nyí jù. Wọ́n gbà pé ìlà tí ó wà ní ojú ẹtu jẹ́ èyí tí ó fún un ní ẹwà yàtọ̀ sí àwọn ẹranko ẹlẹgbẹ́ rẹ̀. Oríkì ẹranko yìí tilẹ̀ fi hàn pé àwọn ọdẹ ní ìfẹ́ àrà ọ̀tọ̀ sí ẹtu, ìdí ni pé bí ẹranko yìí ṣe wuyì lójú àwọn ọdẹ ni wọ́n ṣe ṣẹ̀dá oríkì ẹtu yìí.

Nínú ìwádìí wa sọ́dọ̀ àwọn ọdẹ, wọ́n jẹ́ ká mọ̀ pé ẹtu jẹ́ ẹranko tí ó máa ń sáré púpọ̀ nínú igbó, wọ́n ní ṣùgbọ́n bí ẹtu ṣe lè sáré tó, ó ní àrùn kan lára, àrùn yìí ni awórókó. Wọ́n ní tí awórókó bá ti gbé ẹtu lọ́gán ni yóò ṣubú lulẹ̀, ọdẹ kọ́dẹ tí ó bá wá dé inú igbó ní àkókò náà pẹ̀lú ìrọ̀rùn ni ọdẹ yìí yóò fi pa ẹtu náà.

**Òòrẹ̀gìrì:** Òòrẹ̀gìrì náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko igbó, ó jẹ́ ẹranko kékeré, kò sí ní ìṣọ̀wọ́ àwọn ẹranko abìjà síbẹ̀, ẹranko líle ni. Ìpẹ́ ara rẹ̀ dúró gẹ́gẹ́ bí agbára ti ẹ̀ tí ó máa ń lò nígbà tí ìjàǹbá bá dojú kọ ọ́. Oró tó wà lára ìpẹ́ yìí kò kéré rárá nítorí ẹnu rẹ̀ dàbí abẹ́rẹ́ ni, ẹnikẹ́ni tí ìpẹ́ yìí bá bà lè gba ibẹ̀ lọ sọ́run.

Òòrẹ̀gìrì a bìpẹ́ lára
Ọmọ a fìpẹ́ yan kágbó
Ẹ mú u, ẹ kì í
Tẹran òòrẹ̀ kọ́'un
Òòrẹ ò rẹ́ni tí ó fìpẹ́ ẹ̀ ta
Ní fi ń tagi nínú oko (Àjàyí, 2015)

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú wí pé bí ènìyàn náà ni ẹranko rí, bí ènìyàn bá ní agbára ìfòyà kò ní sí fún un, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà ni ti

àwọn ẹranko wọ̀nyí rí, oríkì òòrẹ̀ fi hàn pé ẹranko yìí kì í bẹ̀rù ohunkóhun nínú igbó nítorí pé ó gbẹ́kẹ̀lé agbára rẹ̀, èyí ni ìpẹ́ tí ó wà ní gbogbo ara rẹ̀.

Àwọn ọdẹ ṣàkíyèsí pé òòrẹ̀ kì í fara pamọ́ nínú igbó, wọ́n gbàgbọ́ pé nítorí ìpẹ́ ara rẹ̀ ni ó ṣe máa ń yan bí ó ṣe wù ú káàkiri inú igbó. Ẹranko yìí máa ń fi ìpẹ́ rẹ̀ dáàbòbo ara rẹ̀ lọ́wọ́ ewukéwu tí ó lè dìde sí i láti ọwọ́ àwọn ẹranko ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ tàbí àwọn ọmọ adáríhunrun.



**Àwòrán 2:** Òòrẹ̀gìrì níbi tí ó ti ń bínú

**Ẹkùn:** Lára àwọn ẹranko alágbára ni ẹkùn wà, ẹkùn ògìdán olóólà ijù jẹ́ ọ̀kan lára ẹranko tí Olódùmarè yọ̀nda agbára fún, ẹranko líle ni ẹkùn, ó sì tún jẹ́ ọlọ́gbọ́n ẹranko, ọgbọ́n yìí ni ó máa ń lò láti fi rí agbára rẹ̀ lò nítorí pé ọgbọ́n ju agbára lọ. Ẹkùn jẹ́ ẹranko tí a fi agbára fún nípa ẹ̀yà ara bíi ti kìnnìún. Èékánná ẹkùn jẹ́ ohun èlò fún-un, òun ni ó máa ń lò láti fi pa yálà ènìyàn ni tàbí ẹranko. Èyí hàn nínú oríkì rẹ̀:

Ẹkùn abìjà-wàrà
Ẹranko a-torí-mẹ́ran jẹ

Alábẹ lọ́wọ́
Olóòlà ijù
Ẹkùn a bìrìn gìnnì
Ẹranko a-jí-polówó ikú tantan
Ẹkùn ògìdán
Olóòlà ijù (Àjàyí, 2015)



**Àwòrán 3:** Àwòrán Ẹkùn lórí ìtàkùn àgbáyé

Ó hàn dájú pé ẹkùn àti kìnnìún ní agbára púpọ̀ lórí àwọn ẹranko inú igbó. Oríkì àwọn méjèèjì ni ó sì fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí alágbára láàrin ẹranko ẹlẹgbẹ́ wọn. Irú agbára tí àwọn ẹranko méjèèjì yìí ní ni ó fa ìpèdè àwọn Yorùbá tí ó sọ pé "kàkà kí kìnnìún ṣakápò ẹkùn, oníkálukú á máa dọ́dẹ ṣe ni". Kò sí èyíkèyí nínú àwọn ẹranko méjèèjì tí ènìyàn lè fojú di rárá. Bí Òyìnbó aláwọ̀ fúnfún ṣe ní ìgboyà tó láti ṣe ohunkóhun tàbí láti wádìí ohunkóhun, wọn kò lè déédéé

kojú àwọn ẹranko méjèèjì láìjẹ́ wí pé wọ́n ti fi ẹ̀wọ̀n dè wọ́n tàbí wọ́n ti kó wọn sí inú ọgbà tí wọn kò ti lè jáde.

**Ìkookò:** Ìkookò jẹ́ ẹranko tí ó ní ìfẹ́ sí jíjẹ eegun. Kò sí bí egungun yìí ṣe tóbi tó tàbí tí ó le tó, ìkookò yóò fọ́ ọ túútú. Ara ìwà àti ìṣe ẹranko yìí nìyí, èyí sì farahàn nínú oríkì ìsàlẹ̀ yìí:

> Òmìrin jáko
> Egungun ọdún mẹ́ta kìkì ọ̀rá
> Òmìrin a bá olókùú sìnkú
> A jẹẹ̀ranjeegun
> Ò jẹ àkọ̀ jẹ panla (Àjàyí, 2015)

Orúkọ mìíràn fún ìkookò ni òmìrín, àyọlò òkè yìí túmọ̀ sí wí pé kò sí ẹranko tí ìkookò kò lè fọ́ eegun rẹ̀, yálà ẹranko inú igbó ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ni tàbí ènìyàn, ẹranko tí ó léwu púpọ̀ ni.

Ìtàn sọ fún wa pé ìkookò máa ń wọ inú ìlú wá láti máa pa àgùtàn jẹ, yóò dara pọ̀ mọ́ àgùtàn. Ó máa ń wa ilẹ̀, yóò gbẹ́ inú ihò láti dé inú ilé láyé àtijọ́ tí yóò sì gbé ọmọ kéékèèké láti pa wọ́n jẹ, àkókò yìí ni àwọn abiyamọ kì í lè é sùn láyé àtijọ́. Oríkì òkè yìí tún tọ́ka si pé kì í ṣe eegun nìkan ni ẹranko yìí fẹ́ràn, àjẹpọ̀ ẹran àti eegun ni oúnjẹ rẹ̀.

**Kìnnìún:** Kìnnìún ni a mọ̀ sí ọba gbogbo ẹranko, agbára tí Olódùmarè fi fún kìnnìún ni ó jẹ́ kí gbogbo ẹranko bẹ̀rù rẹ̀. Ìrísí kìnnìún ẹ̀rù ni, igbe rẹ̀ nínú igbó ẹ̀rù ni. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, Olódùmarè tún fi ìtọ̀ kìnnìún ṣe agbára fún un láti lè máa fi rí oúnjẹ òòjọ́ rẹ̀ jẹ, nítorí pé ìtọ̀ kìnnìún dàbí ẹ̀mú, tí ebi bá ti ń pa kìnnìún, yóò tọ̀ yípo ibi tí ó bá wà, yóò sì bú ramú-

ramù, ibi tí àwọn ẹranko bá ti ń sá àsálà fún ẹ̀mí wọn tí wọ́n bá ti lè tẹ ìtọ̀ yìí mọ́lẹ̀, wọn kò ní lè yẹsẹ̀ mọ́, ìtọ̀ yìí yóò mú wọn mọ́lẹ̀. Ìdí nìyí tí ó tún ṣe hàn nínú oríkì rẹ̀ pé “Dẹ̀rù síjù, fẹran bọnu”. Kìnnìún jẹ́ ẹranko tí ó gbọ́n tí ó sì lágbára.

Oríkì kìnnìún tún jẹ́ ká mọ̀ pé nígbà tí ebi bá ń pa á yóò bẹ̀rẹ̀ sí ní bú ramúramù tí gbogbo ẹranko yóò sì máa sé lu ara wọn títí wọn yóò fi bọ́ sí ọwọ́ ẹkùn, ìdí nìyí tí oríkì rẹ̀ fi sọ pé “Dẹ̀rù síjù, fẹran bọnu” kìnnìún jẹ́ ẹranko tí ó gbọ́n, tí ó sì lágbára.

Tí a bá tún wo àwọn ẹ̀yà ara kìnnìún bíi èékánná, eyín, orí àti ìrù, wọ́n jẹ́ irinṣẹ́ alápatà nítorí tí ó bá gbá ènìyàn tàbí ẹranko ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ mú kíkun ni ó máa ń kun wọ́n, èyí tó hàn nínú oríkì ìsàlẹ̀ yìí:

Kìnnìún olóólà ijù
Pa nígbó, pa níjù
Àkomọ láìlábẹ́
Adámọ-lókó-agbára
Ẹranko tí í forí jà tí ń fìrù jà
Kìnnìún ò jẹran-àn kàsì lẹgàn (Àjàyí, 2015)



**Àwòrán 4:** Kìnnìún níbi tí ó ti ń fa ẹran egbin ya

Yorùbá máa ń sọ pé ọ̀pọ̀ oògùn arumọ gàlègàlè, bẹ́ẹ̀ náà ni agbára tí kìnnìún ní yìí máa ń gùn ún. Ẹranko yìí gbà pé òun le è pa ẹranko tí ó bá wu òun jẹ tàbí ẹ̀dá ènìyàn tí ó bá ṣìnrìn sínú igbó nígbàkúgbà.

**Erin:** Ẹranko mìíràn tí Olódùmarè tún fi agbára jíǹkí ni erin. Erin jẹ́ ẹranko tí ipá ẹranko mìíràn kò lè ká bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀, kò sì sí ohun tí erin kò lè kọlù. Agbára tí Olódùmarè fi jíǹkí erin gẹ́gẹ́ bí ẹranko wà nínú àwọn ẹ̀yà ara rẹ̀. Ọwọ́jà erin jẹ́ ọ̀kan lára ibi tí Olódùmarè fi agbára rẹ̀ sí, ó lè fi ọwọ́jà yìí bi ilé lulẹ̀, ó lè fi wú igi ńlá tìdítìdí. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, àwọn ẹsẹ̀ erin mẹ́rẹ̀ẹ̀rin kìtìpìkìtìpì tí ó fi ń rìn kò sí ẹranko tí erin kò le è fi tẹ̀ pa, èyí hàn nínú oríkì rẹ̀:

Erin Ọlọ́rùn ẹ̀rù  
Ògbólògbó adẹ́tẹ̀, ẹran abìrìn bàtàkùn

Erin Ògbó adẹ́tẹ̀ abìrìn tàmù
Àjànàkú lọ́wọ́ kan ó bi ọ̀pẹ̀ wó
Ibi erin bá ti kọjá
Tigbó tijù ni ó sì mì tìtì
Ọ̀rọ̀ tí í sẹ́gi pó-pò-pó rẹgi
Erin fọwọ́ ọlá yagi bí aṣọ
Abọwọ́jà bíi àpò òjòlá
Ó tẹ gbòǹgbò ọ̀nà soni sùùrùù (Àjàyí, 2015)

Agbára tí àwọn ọdẹ rí nínú ìṣesí erin ni ó mú kí àwọn Yorùbá máa lò ó fún àwọn ìdílé láti máa fi ṣe àyẹ́sí àti àfiwé ara wọn, àti láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn dá wọn mọ̀ gẹ́gẹ́ bí alágbára àti akíkanjú ènìyàn. Bí a bá wo oríkì ìran Onígbòórí, wọ́n fi oríkì wọn sọ díẹ̀ lára ohun tí àwọn ẹ̀yà ara erin kan wúlò fún:

Lérin lérin méje òun ni wọ́n máa ń ki baba
Erin fọlá mi
Erin fìbì yakòó
Ọlá erin tí erin í fi í yagi
Ọ̀rọ̀ gùdùgbẹ̀ nígbésí àlọ
Ìgbẹ́ erin ò ṣe é palé
Ìtọ̀ erin ò ṣe é bù sebè
Sábá erin ṣe é dá
Ìjáǹjá erin ṣe é dá
Ìrọ́kẹ́ erin ṣe é fà lọ́wọ́ fún àwọn ọdẹ
Eyín erin ṣe é rìpó fún àwọn ọba
Ẹran erin ṣe é kàà'wọ fún ifá (Babalọlá, 2002)

Oríkì yìí fi ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin ẹranko yìí àti ìran Onígbòórí hàn. Yàtọ̀ sí èyí, ó tún fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ọlọ́lá, alágbára àti ẹni tí ó ṣe é fi yangàn láwùjọ. Síwájú síi, oríkì yìí jẹ́ ká mọ̀ wí pé wọn kì í tọ̀ṣì nínú ìran Onígbòórí, oríkì wọn

yìí fi wọ́n wé erin nítorí gbogbo ẹ̀yà ara erin pátápátá ni ó wúlò. Ẹ̀yí fi hàn wí pé ìran yìí kì í ṣe ọ̀lẹ àti pé akíkanjú ẹ̀dá ni wọ́n.

Bákan náà ni oríkì ìran Òkò Ìrèsé fi ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin erin àti ìran yìí hàn.

Ọmọ Erin ò-kawọ́n
Ọmọ Erin fáwọn-ó-fàwọ̀n ya
Ọmọ Erin fọláyagi
Ọmọ lówólówó
Ọmọ lọ́rọ̀lọ́rọ̀
Ọmọ A-rààbáá-lè-doògùn
Ọmọ A-dáṣọ-ọ́ lẹ̀ kíyàwó-ó tó dé
Ọmọ Erin jogún ọlá (Babalọlá, 2002)

Oríkì yìí fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ọlọ́lá àti gbajúmọ̀ láàrin ìlú. Ó tún jẹ́ ká mọ̀ pé alágbára ni wọ́n gẹ́gẹ́ bí erin ṣe jẹ́ alágbára láàrin àwọn ẹranko yòókù. Yàtọ̀ sí èyí, oríkì àwọn Òkò Ìrèsé tún fi hàn pé ènìyàn iyì ni wọ́n ń ṣe. Ó tún hàn nínú oríkì wọn pé alágbára àti jagunjagun ni wọ́n. Wọ́n lówó lọ́lá, wọ́n sì tún ní oògùn, parípari gbogbo rẹ̀ ni wí pé wọn kì í ṣe ọ̀lẹ, èyí ń jẹ́ kó yé wa pé akíkanjú ẹranko ni erin ń ṣe láàrin àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀ yóókù nínú igbó.

A tún rí àwọn ìlú kan ní ilẹ̀ Yorùbá tí ó jẹ́ pé orúkọ erin ni wọ́n máa ń kì wọ́n mọ́. Ìlú Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí jẹ́ ọ̀kan lára irú ìlú bẹ́ẹ̀. Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ni ìlú Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí wà, ìlú yìí kún fún àwọn ẹranko ńlá ńlá bíi erin, ẹfọ̀n, túùkú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ṣùgbọ́n nínú gbogbo àwọn ẹranko tí a dárúkọ sókè yìí, erin nìkan ni à ń ki àwọn ìlú yìí mọ́. Oríkì yìí sọ pé, "Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí ọmọ erin fọlá mí, ọmọ erin fọlá yagi". Ní ìbámu pẹ̀lú oríkì yìí, wọ́n mọ

ère erin kan sí ìkòríta tó lọ sí ààfin ọba Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí. Ère erin yìí ń júwe àwọn ará ìlú Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí gẹ́gẹ́ bí akíkanjú, alágbára àti akọni ènìyàn.

## Àgbálọgbábọ̀

Àǹfàní ńláńlà ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé ń fún àwùjọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun tí kò yé wa nípa àwọn ẹranko ni a ti ṣàlàyé nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí pàápàá jùlọ nípa àwọn ẹranko afàyàfà àti àwọn ẹranko búburú. A ṣe àkíyèsí pé àwọn ẹranko afàyàfà kan wà tí ó lè gbé ènìyàn mì lódidi gẹ́gẹ́ bí ìtàkùn àgbáyé ṣe fi hàn wá. Bákan náà ni a ṣe àfihàn ìrísí àti ìṣesí àwọn ẹranko wọ̀nyí. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, ogunlọ́gọ̀ àǹfààní ni a rí nínú ṣíṣe àmúlò ìtàkùn àgbáyé nípa níní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ẹranko láàrin àgbà àti èwe. Bí àpẹẹrẹ, ìtàkùn àgbáyé ni ó jẹ́ kí á ní àǹfààní láti lè máa rí àwọn ẹranko wọ̀nyí lójúkojú, ó ń jẹ́ kí á mọ ìhùwàsí àti ìṣe wọn, ó tún fún wa ní àǹfààní láti lè jẹ́ ká mọ irúfẹ́ oúnjẹ tí wọ́n ń jẹ, ibùgbé wọn àti ìbáṣepọ̀ wọn pẹ̀lú àwọn ẹranko mìíràn. Bákan náà ni a tilẹ̀ ní àǹfààní láti ní ìkànnì kan lórí ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán èyí tí à ń pè ní “National Geographical”. Ẹranko nìkan ni wọ́n máa ń ṣe àfihàn ní ìkànnì yìí, oríṣiríṣi nǹkan ni wọ́n sì máa ń sọ nípa àwọn ẹranko wọ̀nyí fún aráyé. A wá rí i pé àfikún àti àǹfàní ló jẹ́ fún ìran tí a wà yìí láti lè jẹ́ kí á ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ẹranko tí wọn kò tí ì rí rí tàbí tí wọn kò tí ì gbọ́ nípa wọn rí lórí ìtàkùn àgbáyé. Lára àǹfàní yìí ni àwọn ẹranko líle tí a rí àwòrán wọn lórí ìtàkùn

àgbáyé, èyí fi hàn pé ẹni tí kò bá mọ bí irú ẹranko wọ̀nyí ṣe burú tó ní kété tí ó bá ti rí àwòrán yìí ni yóò ti mọ irú ewu tí ó lè wu ẹnikẹ́ni tí ó bá rìnnà pàdé irú ẹranko bẹ́ẹ̀. Iṣẹ́ yìí wá ń fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìmọ̀ nípa àwọn ẹranko lórí ìtàkùn àgbáyé jẹ́ àfikún ìmọ̀ fún àwọn ọ̀dọ́ ìwòyí àti gbogbo ènìyàn lápapọ̀.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Adéríbigbé, M. (2008). *Òkété*. Abẹ́òkúta: Bean Print Executive and Co.

Agba, G. (2002). *Communication in Global ICTs & Ecosystem Perspectives – Insight from Nigeria*. Enugu: Precision Publishers Limited.

Àjàyí, O.T. (2011). "Àgbéyẹ̀wò Oríkì àwọn Àṣàyàn Ẹranko Nínú Ìjálá àti Ìrèmọ̀jé". M.A. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Àjàyí, O.T. (2015). "Àgbéyẹ̀wò Ojú Àmúwayé Yorùbá Nípa Ẹranko nínú Oríkì, Ẹsẹ-Ifá, Ọfọ̀ àti Ìjálá". Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Ajíbádé, G.O. (2003). "Àgbéyẹ̀wò Awo Ọ̀ṣun àti Àwùjọ Òṣogbo nínú Iṣẹ́ Ọnà Ajẹméwì àti Ajẹmáwòrán" Department of African Languages and Literature. Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Ajíbádé, G.O. (2005). "Animals in the Traditional Worldview of the Yorùbá Folklore" 30 (3):155-172. Vol. 3.

Atiládé, E.A. (1963). *Ìwé Oríkì Àwọn Orílẹ̀ Yorùbá*. Lagos: Atiládé Press.

Davey, S.L. (1999). *International Encyclopedia of the Social Sciences*. London: Collier Macmillian Publishers.

Eagleton, T. (1983). *Literary Theory: An Introduction*. New York: Brazil Blackwell Publishers Ltd.

Ọláfimíhàn, J. (1953). *Àwọn Ẹdá Alàyè*. London: Longmans, Green and Co. Ltd.